Eyi tó lọ́lá jùlọ ninu awọn iranti Ọlọhun ni gbolohun: LAA ILAAHA ILLALLOOH, eyi tó sì lọ́lá jùlọ ninu awọn adura ni gbolohun: ALHAMDULILLAH

Lati ọdọ Jabir - ki Ọlọhun yọnu si i - ó sọ pé: Mo gbọ Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - tí n sọ pé: "Eyi tó lọ́lá jùlọ ninu awọn iranti Ọlọhun ni gbolohun: LAA ILAAHA ILLALLOOH, eyi tó sì lọ́lá jùlọ ninu awọn adura ni gbolohun: ALHAMDULILLAH".

[O daa] [Tirmiziy ati Nasaa'iy ni wọn gba a wa ninu al-Kubrọ, ati Ibnu Maajah]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n sọ fún wa pé iranti Ọlọhun tó lọ́lá jùlọ ni: "LAA ILAAHA ILLALLOOH" itumọ rẹ ni pé kò sí nkankan tí a gbọdọ̀ jọsin fun pẹlu ododo ayafi Ọlọhun Allah, ati pé adura tó lọ́lá jùlọ ni ALHAMDULILLAH; iyẹn ni pé a n fi rinlẹ pé dajudaju Allahu ni Oluṣedẹra fún wa, Oun ni O sì lẹtọọ si iroyin tó pé, tó sì dara julọ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3567